# ÀÀBÒ ATI AYỌ̀ OLODODO

## Orin Dafidi 91:1-16

## ẸKỌ 83 -- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Yio fi iyẹ́ rẹ̀ bò ọ, abẹ iyẹ́-apa rẹ̀ ni iwọ o si gbẹkẹle: otitọ rẹ̀ ni yio ṣe asà ati apata rẹ" (Orin Dafidi 91:4).**

**I Aṣiiri Nini Itọju Ọlọrun**

1. Adura jẹ́ ohun aigbọdọ má ṣe – "On o pè orukọ mi," Orin Dafidi 91:15; Iṣe Awọn Apọsteli 2:21
2. Kika Ọrọ Ọlọrun ṣe pataki – "Otitọ rẹ̀ ni yio ṣe asà rẹ," Orin Dafidi 91:4; Jobu 23:12; Orin Dafidi 119:11
3. Igbagbọ jẹ́ iṣẹgun – "Ẹniti emi gbẹkẹle," Orin Dafidi 91:2; 1 Johannu 5:4
4. Wiwà lọna naa ṣe danindanin – "Ẹniti o joko . . ." Orin Dafidi 91:1, 9; Matteeu 10:22
5. Fifẹ́ ati mimọ Ọlọrun mú idaniloju igbala ayeraye wá, Orin Dafidi 91:14; Johannu 17:3; Orin Dafidi 9:10

**II Idaniloju Aabo Ọlọrun**

6. "On o gbà ọ," Orin Dafidi 91:3
7. "Ẹgbẹrun yio ṣubu.ṣugbọn ki yio sunmọ ọdọ rẹ" Orin Dafidi 91:7, 8
8. "Yio fi aṣẹ fun awọn angẹli rẹ̀ nitori rẹ," Orin Dafidi 91:11, 12; Heberu 1:13, 14

**III Diẹ ninu awọn Eredi Ayọ̀**

9. "Iwọ kì yio bẹ̀ru," Orin Dafidi 91:5, 6; 2 Timoteu 1:7
10. "Buburu kan ki yio ṣubu lu ọ,"Orin Dafidi 91:10
11. "Ẹmi gigun li emi o fi tẹ́ ẹ lọrun, emi o si fi igbala mi hàn a," Orin Dafidi 91:16
12. Awọn ẹni iwa-bi-Ọlọrun jẹ́ aṣẹgun – "Iwọ o kọja lori kiniun," Orin Dafidi 91:13
13. "Emi o si bu ọlá fun u," Orin Dafidi 91:15

## ALAYE

Saamu yii fi itọju Ọlọrun fun awọn ti Rẹ̀ hàn. O n fi aworan hàn wa bi Ọlọrun ti i kó awọn eniyan Rẹ̀ si ibi aabò labẹ iyẹ Rẹ̀ gẹgẹ bi adiẹ ti i ràdọ̀ bo awọn ọmọ rẹ̀. "Yio fi iyẹ́ rẹ̀ bò o, abẹ iyẹ́-apa rẹ̀ ni iwọ o si gbẹkẹle." Jesu ṣe apejuwe kan naa nigba ti O sọ nipa ifẹ Rẹ̀ si Jerusalẹmu, "Nigba melo li emi nfẹ iradọ bò awọn ọmọ rẹ, bi agbebọ̀ ti iradọ bò awọn ọmọ rẹ̀ labẹ́ apá rẹ̀, ṣugbọn ẹnyin kò fẹ!" (Luku 13:34).

Nigba wahala ọpọ eniyan ni o maa n fẹ igbala ati aabo Ọlọrun, ṣugbọn wọn ki i fẹ ṣe ohun ti o yẹ fun wọn lati ṣe ki wọn to le bọ́ si abẹ́ iyẹ́ apa Rẹ̀. Awọn ileri ti o wà ninu Saamu yii jẹ ti awọn ti wọn wà nibi ikọkọ Ọga Ogo. Nipa Ẹjẹ Kristi ni a le gbà de ibẹ̀. Ki ẹnikẹni to le maa gbé ibi ikọkọ yii, o gbọdọ ti ronupiwada ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ki o si ti ri idariji gbà. "Nitori ti o mọ̀ orukọ mi," eyi fi idapọ pẹlu Ọlọrun hàn, ti ọkàn atunbi nikan ṣoṣo maa n ní. "Iye ainipẹkun na si li eyi, ki nwọn ki o le mọ̀ ọ, iwọ nikan Ọlọrun otitọ, ati Jesu Kristi, ẹniti iwọ rán" (Johannu 17:3).

### Gbigbé inu Ọlọrun

Nigba ti ẹni kan ba wà ni ibi ikọkọ (ti o di atunbi ni tootọ), o ṣe dandan ki o maa gbé ibẹ ki o ba le jẹ́ ajogun aabo ti a fi fun un. Ki a lo aworan ti adiẹ bi apẹẹrẹ, ọmọ adiẹ gbọdọ wà labẹ agbebọ-iya rẹ, fun aabo ati ipamọ; bẹẹ gẹgẹ ni awa naa ni lati maa gbé labẹ ojiji iyẹ́ apá Olodumare. Niwọn bi Bibeli ti sọ pe, "Nitori iwọ ti fi OLUWA …. ṣe ibugbe rẹ," nitori bẹẹ ni a ṣe ni lati maa gbé inu Oluwa nigba gbogbo. O ṣe e ṣe ki eniyan ti ri igbala lẹẹkan ki o si ti wà labẹ aabo Ọlọrun Olodumare, lẹyin naa ki o si ṣako lọ, ki o si ṣegbe laelae. Nitori naa o ṣe danindanin ki a maa wà loju ọna naa nigba gbogbo. Jesu wi pe, "Bi ẹnyin ba duro ninu ọ̀rọ mi, nigbana li ẹnyin jẹ ọmọ-ẹhin mi nitõtọ" (Johannu 8:31). Iṣẹ́ ti Ọlọrun rán nipasẹ Esekiẹli ni pe, "Ododo olododo ki yio gbà a là li ọjọ irekọja rẹ̀" (Esekiẹli 33:12). Bi iwọ ba jẹ́ ọ̀kan ninu awọn ti o ti fi abẹ aabo Rẹ̀ silẹ, o wà nipo ewu, nitori bi o ba kú ninu ẹ̀ṣẹ rẹ, iwọ yoo ṣegbe laelae. Tete pada sabẹ itọju Rẹ̀ (Esekiẹli 33:11; Deuteronomi 33:27).

### Adura

Ọ̀kan ninu awọn ohun ti Onigbagbọ́ ni i ṣe lati wà ninu Oluwa ni lati maa gbadura pupọ. "On o pè orukọ mi." Jesu ti ṣe ileri fun wa pe, "Ohunkohun ti ẹnyin ba si bère li orukọ mi, on na li emi ó ṣe" (Johannu 14:13). Oun si tun kọ́ wa pe "O yẹ ki a mã gbadura nigbagbogbo" (Luku 18:1).

### Ọrọ Naa

Ẹni ti n gbé ibi ikọkọ Ọga Ogo gbọdọ rọ̀ mọ́ Ọrọ Ọlọrun fun agbára ati itọni. "Otitọ rẹ̀ ni yio ṣe asà ati apata rẹ." Nigba ti eṣu dán Jesu wò, Jesu lọ sinu Ọrọ Ọlọrun. Nipa diduro lori Ọrọ Ọlọrun ni ọpọlọpọ awọn iranṣẹ Ọlọrun fi le la iṣoro pupọ já. Ọmọ ogun kan ninu ọkọ ogun ofurufu, ni akoko ogun Ajakaye keji, sọ pe awọn ileri Saamu yii ni oun rọ̀ mọ́ ni igba marundinlogoji ti oun gbé ọkọ̀ fò la orilẹ-ède Japan já. Awọn ileri wọnyii ni wọn gbe e rekọja ewu ikú¸ ti wọn si fun un ni aabo lọwọ ogun ọta ni ofurufu. O pada si ile ni alaafia bi o tilẹ jẹ pe ninu irin ajo rẹ kan, bọmbu kan bú gbàmù ni nnkan bi ẹsẹ̀ bata meji lẹyin rẹ̀ nibi ti o wà ninu ọkọ̀ ofurufu rẹ̀.

### Igbagbọ́

"Ẹniti emi gbẹkẹle." Igbagbọ́ nikan ṣoṣo ninu Ọlọrun ni o le mu ki a duro ṣinṣin lori awọn ileri Rẹ̀. Lai si igbagbọ kò ṣe e ṣe lati wu Ọlọrun. Ṣugbọn ẹ wo ohun ribiribi ti igbọran si aṣẹ Rẹ̀ maa n yọri si! Jesu wi fun ọkunrin afọju naa pe. "Mã lọ; igbagbọ́ rẹ mu ọ larada" (Marku 10:52). Bibeli sọ fun ni pe nipa igbagbọ́ ni awọn ara igba ni "ṣẹgun ilẹ ọba, ti nwọn ṣiṣẹ ododo, ti nwọn gbà ileri, ti nwọn dí awọn kiniun li ẹnu, ti nwọn pa agbara ina, ti

nwọn bọ́ lọwọ oju-idà, ti a sọ di alagbara ninu ailera, ti nwọn di akọni ni ija, nwọn lé ogun awọn àjeji sá" (Heberu 11:33, 34).

**Aabo**

"Iwọ ki yio bẹru." Ileri iyanu wo ni eyi! Kò si ohun ti ọmọ eniyan kò le ṣe tan lati pa ara rẹ mọ́ kuro lọwọ ohun wọnni ti o n bẹru. Eniyan ti ṣe ofin ati eto pupọ lati daabo bo ara rẹ̀ lọwọ ipọnju aini nigba ajalu, aisan ati ọjọ ogbo. Ṣugbọn ninu Ọlọrun nikan ni a le ni ominira kuro lọwọ ibẹru. Igbẹkẹle nla ni a fi fun Onigbagbọ́ nipa mimọ̀ pe "ohun gbogbo li o nṣiṣẹ pọ̀ si rere fun awọn ti o fẹ Ọlọrun" (Romu 8:28). Aabo Ọlọrun fun awọn eniyan Rẹ̀ ti fara hàn ni igba pupọ. Wo ti itọju Rẹ̀ fun awọn Ọmọ Israẹli lati Egipti lọ si ilẹ ileri. "Yio fi aṣẹ fun awọn angẹli rẹ̀ nitori rẹ" jẹ́ idaniloju pe kò si ibi ti yoo ṣẹlẹ si Onigbagbọ́ bi Ọlọrun kò ba fi aafo rẹ̀ silẹ. Ireti ati iṣura Onigbagbọ wà ni Ọrun, nitori bẹẹ ko le jamọ nnkan kan fun un ti o ba wu Ọlọrun lati mu un lọ nigbakigba boya ni èwe tabi ni àgbà. Ninu ayé yii nikan ni ireti eniyan buburu wà, "ère awọn enia buburu" yoo jẹ́ lẹyin ayé yii ni iparun ayeraye. Nigba miiran Onigbagbọ́ ati ẹlẹṣẹ le jọ ṣubu loju ogun kan naa ki wọn si kú, ṣugbọn dajudaju ère wọn yatọ si ara wọn patapata. Ẹmi Onigbagbọ yoo lọ si Ọrun rere lẹsẹ kan naa, ṣugbọn ẹmi ẹlẹṣẹ yoo lọ si inu àjookú iná ọrun apaadi.

**Iṣẹgun**

"Iwọ o kọja lori kiniun ati pamọlẹ." Ki i ṣe aabo lọwọ ọta ọkàn nikan ni Onigbagbọ́ ni, ṣugbọn a fun un ni agbara lati jade lọ soju ija pẹlu. Eredi ni yii ti Paulu fi le sọ pe, "Ṣugbọn ọpẹ́ ni fun Ọlọrun ẹniti o fi iṣẹgun fun wa nipa Oluwa wa Jesu Kristi" (I Kọrinti 15:57). Ileri Ọlọrun fun Israẹli ni pe, "Ọkunrin kan ninu nyin yio lé ẹgbẹrun" (Jọṣua 23:10). Awọn ileri iṣẹgun ti ode ara ti a ṣe fun Israẹli kò tobi ju ileri iṣẹgun nipa ti ẹmi ti a ṣe fun awọn eniyan Ọlọrun lọjọ oni. Saamu ayọ̀ iṣẹgun yii pari pẹlu awọn ileri idande, ọla, ẹmi gigun, itẹlọrun, ati igbala.

## AWỌN IBEERE

14. Ki ni itumọ ki eniyan maa gbé "ibi ikọkọ Ọga-ogo"?
15. Ki ni itumọ "ikẹkun awọn pẹyẹpẹyẹ," ki ni ohun ti ẹmi ti iwọ le mu jade nibẹ?
16. Iwe Mimọ́ wo ni o fi ara jọ ẹsẹ keje?
17. Iyatọ wo ni o wà laaarin ère awọn eniyan buburu ati ti awọn olododo?
18. Ta ni olupamọ awọn olododo? Iwe Mimọ́ miiran wo ni o jẹri si eyi?
19. Wá ẹsẹ mẹta ninu Saamu yii ti o fi hàn pe awọn ileri ti o wà ninu iwe yii wà fun awọn ti a ti dari ẹṣẹ wọn ji.
20. Ẹsẹ wo ni o fi igbagbọ́ ninu Ọlọrun hàn?
21. Ka gbogbo ileri ti o wà ninu Saamu yii.